# ỌRỌ̀ TI ẸMI

**Isaiah 58:1-14**

**ẸKỌ 368 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ṣe inu-didùn si OLUWA pẹlu, on o si fi ifẹ inu rẹ̀ fun ọ" (Orin Dafidi 37:4).**

**Ifetisilẹ**

Nigba ti Isaiah Wolii wi pe, "Gbe ohùn rẹ soke bi ipè," ohun ti o n sọ ni pe "Fun fere", tabi "Ké ibosi idagiri." Ohun ipè ma a n sọ fun awọn eniyan lati feti silẹ. Laaarin awọn ologun, fifun ipè ogun ma a n ji awọn ọmọ-ogun lowurọ; àmi miiran a si tun kilọ fun un pe ọ̀tá sunmọ tosi; àmi miiran ẹwẹ si ni pe "ki a pa gbogbo iná" ti o wà ninu ọgba awọn ọmọ-ogun; wọn tun ma a n fun ipe nibi isinku awọn ọmọ-ogun.

Ki ni ṣe ti Isaiah fi n fẹ ki "ipè dún"? Ọran awọn Ju ni o jẹ ẹ lọkàn to bẹẹ ti o si n fẹ fi ẹ̀ṣẹ wọn han wọn. Gẹgẹ bi o ti ri fun ọ̀pọlọpọ eniyan lọjọ oni, wọn n fi ara wọn pe ohun ti wọn kò jẹ. Ni ode-ara wọn ni afara wé iwa-mimọ́ ṣugbọn wọn kò ni iwa-mimọ́ ti inu. Gbogbo eto isin ni wọn n kiyesi finnifinni, ṣugbọn ọkàn wọn kún fun iwa buburu.

**Adura ati Aawẹ**

Wọn maa n gbadura ni ojoojumọ wọn si maa n gbaawẹ̀ nigba gbogbo. Wọn rò pe, dajudaju, Ọlọrun ni lati gbọ́ ti wọn. Ni akoko ti Jesu wà ni ayé awọn miiran ninu awọn eniyan yii ma a n ba oju jẹ nigba ti wọn ba n gbaawẹ̀, iduro wọn a si dabi ti ẹni ti inu rẹ̀ kò dùn. Jesu pè wọn ni agabagebe. O ni nigba ti awọn eniyan ba n gbaawẹ n ṣe ni o yẹ ki wọn wẹ oju wọn, ki wọn má si fi ara hàn rara bi ẹni ti n gbaawẹ̀. Baba ti n bẹ ni Ọrun nikan ni O mọ̀ igba ti Onigbagbọ́ n sẹ ara rẹ̀ nipa ounjẹ ti o si fi ara rẹ̀ fun adura pupọ. Kò yẹ ki ẹlomiran mọ̀.

Nigba ti Oluwa ba fi iwuwo pataki kan sinu ọkàn ẹni kan lati gbadura fun ohun kan, o gbọdọ gbaawẹ. Ni igba miiran iwuwo adura fun alaisàn tabi fun alaigbagbọ́ kan le ṣe pataki to bẹẹ ti eniyan kò tilẹ ni le ronu nipa ounjẹ. Ohun ti o ṣe danindanin ninu rẹ̀ ni lati ṣe e pẹlu otitọ ọkàn ati fun kiki ogo Ọlọrun nikan ṣoṣo, ki i ṣe lati fi wu eniyan.

Isaiah sọ fun awọn Ju: "Ẹ máṣe gbãwẹ bi ti ọjọ yi, ki a le gbọ́ ohùn nyin li oke." "Lati tẹ ori rẹ̀ ba bi koriko odò? ati lati tẹ́ aṣọ ọ̀fọ ati ẽru labẹ rẹ̀?" Isaiah sọ wi pe isin tootọ jẹ eyi ti o ma a n ran awọn ti wọn ni ẹru wuwo lọwọ, lati ma a fi ounjẹ fun awọn ti ebi n pa, lati ma a ran awọn alaini lọwọ, lati ma a fi aṣọ bo awọn ti o wà ni ihoho, lati ma a fi aanu ati inu-rere hàn fun awọn eniyan. O ni eyi ṣe pataki ju ki a kàn ma a pariwo lasan ninu adura.

Ẹni kan le wá si ẹnu ọna ile rẹ ti ki i ṣe kiki ounjẹ lati jẹ nikan ni o n fẹ, ṣugbọn ti o yẹ ki o mọ̀ nipa Ihinrere. Sọ nipa Oluwa fun ẹni naa, rọ̀ ọ lati wá si ile-isin, fun un ni Bibeli tabi iwe-itankalẹ Ihinrere, ki o si gbadura fun un. Nigba naa Oluwa yoo mọ̀ pe iwọ n fi ijẹwọ igbagbọ́ rẹ ṣe iwa hù. Nigbakuugba ti iwọ ba ke pe E, Oun yoo si dahun pe, "Emi nĩ."

**Otitọ-inu tabi Iwa-ẹtan**

Wolii naa tun sọ pe bi wọn yoo ba fi aanu ati inu-rere hàn ati ki wọn si ṣaanu fun awọn alaini, nigba naa ni inu Ọlọrun yoo yọ́ si wọn, bi wọn ba si ke pe E, Oun yoo dahun wi pe, "Emi nĩ." Ọlọrun maa n gbọ́ adura atọkànwá ẹni ti o fi otitọ-inu wá iranlọwọ ti o si ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun.

Ẹ jẹ ki a ranti pe Ọlọrun mọ̀ bi o ba ṣe pe tọkàntọkàn wa ni a fi n beere tabi bẹẹ kọ. Nigba ti a ba n ba Ọlọrun sọ̀rọ, a kò le ni ohun kan lọkàn wa ki a si ma a fi ẹtan sọ ohun miiran jade. Nigba miiran awọn eniyan maa n tan awọn miiran jẹ -- awọn ọmọde le "tan" olukọ Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi jẹ tabi ki wọn ṣe "apamọ-pa-bò" fun awọn obi wọn tabi ki wọn tilẹ gbiyanju lati tan alufaa paapaa jẹ. Ṣugbọn ranti pe "A kò le gàn Ọlọrun."

**Ere Jijẹ Oloootọ**

Wo bi o ti dun to lati fara mọ Oluwa timọtimọ ki a si ni ọkàn ati inu ti O ṣipaya si I! Nigba ti iru ẹni bẹẹ ba lọ sori eekun rẹ lati gbadura, Oluwa a si da a lohùn pe, "Emi nĩ." Ninu Johannu 15:7, a kà bayi pe, "Bi ẹnyin ba ngbé inu mi, ti ọ̀rọ mi ba si ngbé inu nyin, ẹ o bère ohunkohun ti ẹ ba fẹ, a o si ṣe e fun nyin."

Wo alaafia nla ti o maa n kún inu ọkàn ẹnikẹni ti n ba Oluwa rin timọtimọ! Isaiah fi iru ọkàn bẹẹ wé ọgbà ti a n bomi rin ati orisun omi ti ọ̀dá ki i dá. Onipsalmu ni iru ẹni bẹẹ yoo dabi "igi ti a gbìn si eti ipa odò, ti nso eso rẹ jade li akokò rẹ; ewe rẹ ki yio si rẹ; ati ohunkohun ti o ṣe ni yio ma ṣe dede" (Orin Dafidi 1:3). Njẹ o le fi oju-inu wo aworan ọgba kan, ni apa ila-oorun, ti o kun fun oriṣiriṣi itanna oloorùn didùn, ọ̀pọlọpọ isun ati orisun omi, ati omi ṣẹlẹrú, awọn ẹyẹ ti n kọrin, ti ọ̀na ati abuja lu já ara wọn, ati nibi ti itura ti o ti Ọrun wá wà ni gbogbo igbà?

### Ọjọ OLUWA

Ikilọ kan ti a tun fi fun ni si i ninu ẹ̀kọ́ yii ni lati ya Ọjọ Isinmi si mimọ́. Ọ̀kan ninu awọn Ofin Mẹwaa ti a fi fun awọn Ọmọ Israẹli ni ọ̀pọlọpọ ọdún ṣiwaju akoko Isaiah ni: "Ranti ọjọ́ ìsimi, lati yà a simimọ́" (Ẹksodu 20:8). Ọjọ kin-in-ni ọsẹ di ọjọ ti a yà sọtọ lati maa jọsin ni ẹsẹkẹsẹ ti Jesu ti jinde; lati igba naa wa ni gbogbo awọn Onigbagbọ́ tootọ ti n pa ọjọ naa mọ́ titi di ọjọ oni. Ọjọ yii ni Jesu jinde kuro ninu okú; aayá ọjọ yii gan an ni O maa n fara hàn awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀; ọjọ yii gan an ni a fi Ẹmi Mimọ́ fun ni ti a si gbe Ijọ tootọ kalẹ; ayá ọjọ naa gan an ni awọn ọmọ-ẹyin maa n pade lati bu akara ni iranti Ounjẹ Alẹ Oluwa, ti wọn si maa n mu ọrẹ wọn wá fun Oluwa.

Ọjọ Oluwa ni ọjọ yii i ṣe a si gbọdọ bu ọlá fun un, a gbọdọ ya a si mimọ́. Gbogbo iṣẹkiṣẹ, tita tabi rira ni Ọjọ-ọsẹ, jẹ́ tita abùkù fun Ọjọ Rẹ̀. Ririn kiri fun igbadun ara ẹni, lilọ luwẹ lodo tabi kiko-ẹgbẹ eré kiri ni Ọjọ Oluwa jẹ ṣiṣe "afẹ́ rẹ." A sọ fun ni pe bi a o ba yi pada kuro ninu ṣiṣe afẹ́ wa ni ọjọ mimọ́ yii ki a si bu ọla fun Ọlọrun, nigba naa inu Rẹ̀ yoo dun si igbesi-ayé wa. O si ṣe ileri pe Oun yoo mu ki a "gùn ibi giga aiye" -- gẹgẹ bi jagunjagun alagbara ti o ti ṣẹgun ti i gun kẹkẹ nla, ti i si maa rin yi awọn oke ka ati ti i ma jẹ igbadun gbogbo ohun didara-didara ayé. Bi o tilẹ jẹ pe ohun diẹ ni Onigbagbọ́ ni lati lò, sibẹ o ni itẹlọrun ati ayọ, nitori pe o ni Jesu; gbogbo aini rẹ ani ju bẹẹ lọ ni a n pese fun lojoojumọ. Ohun ti o n lepa ni lati to "iṣura" jọ si Ọrun.

### Ailoṣuwọn Ibukun

Ẹni kan ti o ti lo ọpọlọpọ ọdun ninu Ihinrere maa n sọ ninu ẹri rẹ nigba gbogbo pe nigba ti Ọlọrun gba ọkàn oun là, oun ni igbadun tootọ ju ti igbakuugba ninu igbesi-ayé rẹ atẹyinwa: o n rin irin ajo-ju ti atẹyinwa, o n wọ aṣọ ti o nilaari ju ti atẹyinwa, o n jẹ ounjẹ ti o dara o si n gbadun igbesi-ayé rẹ gidigidi ju igba ti kò i ti i ni igbala; nitootọ, gbogbo ohun ti o dara ju lọ ninu ayé wà ni iṣura fun ọkunrin, obinrin, ọdọmọkunrin tabi ọdọmọbinrin naa ti o ba fi tọkàntọkàn rẹ sin Oluwa. Ṣugbọn ju gbogbo wọnyii lọ ère nlá nlà n duro de e ni Ọrun.

Iwọ ha n fẹ jẹ́ ọlọrọ̀? Lepa ọrọ̀ ti ẹmi, "Ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin" (Matteu 6:33).

## AWỌN IBEERE

1 Awọn ta ni Isaiah n ba sọ̀rọ̀?

2 Bawo ni wọn ti n gbadura nigba gbogbo si?

3 Ki ni ohun ti wọn n ṣe lati fi mu ki Ọlọrun gbọ́ ti wọn?

4 Njẹ o ro pe wọn jẹ olootọ?

5 Awọn ileri wo ni a ṣe ninu ori iwe ti a ka yii fun awọn ti o gbọran si Oluwa?

6 Njẹ o tilẹ le fi ọ̀rọ ẹnu ṣe apejuwe eniyan ti o gbọran si Oluwa?

7 Ki ni Isaiah fi iru eniyan bẹẹ wé? Ki ni Onipsalmu sọ nipa iru eniyan bẹẹ?

8 Ọjọ wo ni a mọ̀ gẹgẹ bi Ọjọ Oluwa?

9 Awọn ileri wo ni a ṣe fun awọn ti n yà a si mimọ́? (Isaiah 58:14).

10 Sọ idi mẹwaa ti Onigbagbọ́ fi ni inudidùn ju ẹlẹ̀ṣẹ̀ lọ.